# Ògùn Pàjáwìrì Oníkóró Tí Ó Ń Dènà Oyún Níní



### Àlàyé nípa rẹ̀:

- Ògùn pàjáwìrì oníkóró (ECPs) tí ó ń dènà oyún níní jẹ́ èyí tí kò léwu, tí wọ́n sì ǹ ṣiṣẹ́ dáada ní dídènà oyún níní lẹ́yìn ìbálòpọ̀ lai ní ìdábọ̀bọ̀.
- Ó jẹ́ ẹ̀yà ògùn oníkóró tí ó ń dènà oyún níní.
- Ògùn pàjáwìrì oníkóró yìí lè dènà oyún ó pẹ́ tán ọjọ́ márùn lẹ́yìn tí a bá ní ìbálòpọ̀ tí kò ní ídábòbò.
- A gbọ́dọ̀ tètè lò ó láìfasìkò-ṣòfò lẹ́yìn ìbálòpọ̀ tí kò ní ídábòbò. Bí a bá ṣe tètè lò ó sí lẹ́yìn ìbálòpọ̀, ló ma ṣe lè dènà oyún.

### Bí ó ti lè dènà oyún sí:

ECPs le dènà ìdá márùn-dín-lọ́gọ́rin sí ìdá márùn-dín-lọ́gọ̀rún nínú ọgọ́rún ìṣẹ̀lẹ̀ oyún níní tó yẹ kọ́ wáyé tí a bá lò ó láàrin ọjọ́ márùn lẹ́yìn ìbálòpọ̀ tí kò ní ídábòbò.

### Bí óṣe ń ṣiṣẹ́:

- ECPs lè jẹ́ kóró méjì tàbí ẹyọ kan.
- Ẹ tẹ̀lẹ́ ìtọnisọ́nà tí wọ́n kọ sínú àwọn ìwé pélébé láti lò ó.
- Ògùn náà ní èròjà ara (progestin) nínú tí yíò mú ikun tí ówà ní enu ọ̀nà ilé ọmọ kí ó ki, èyí yí ò dènà kí àtọ̀ okùnrin má lè wọ ilé ọmọ.
- Ògùn náà kì jẹ́ kí obìnrin yé ẹyin tí ópọ̀n ní oṣoosù

### Àkíyèsí pàtàkì:

- Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ pàjáwìrì ni ECPs wà fún, kò wà fún lílò ní gbogbo ìgbà.
- A kò gbọdọ̀ lò ó ju ẹ̀meji lọ lóṣù kan.
- Ó ṣeéṣe kí ECP má ṣiṣẹ́ tó yẹ kó ṣe tí a bá lò ó léraléra gẹ́gẹ́ bí ògùn tí ó ń dènà oyún
- ECPs kò lè nípa kankan lórí oyún tó ti fi gbòǹgbò sọlẹ̀ nínú ara
- Ìgbà tí a bá lo ECPs lẹ́yìn ọjọ́ péréte lẹ́yìn ìbálòpọ̀ ló le dènà oyún.
- Kọ̀ dènà àrùn ìbálòpọ̀ tàbí HIV.

### Àànfàní:

- Kò léwu fún gbogbo obìnrin yálà nípa ipò tí ìlera ara wa tàbí ọjọ́ orí.
- ECPs wà ní gbogbo ilé ìwòsàn àti àwọn ilé-ìtajà ògùn.
- Wọ́n máa n´mu´àdínkù bá wàhálà oyún ṣíṣẹ́ àti oyún tí a kò gbaradì fún.
- ECPs kò le ṣàkóba´kankan fún oyún inú.

### Fún àlàyé lẹ́kúnrẹ́rẹ́´sii lórí ECPs:

- Ẹ ka àwọn àlàyé tó wà nínú ìwé pélébé atọ́nisọ́nà
- Ẹ ṣàbẹ̀wò sódò akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ nípa ìfètòsọ́mọ bíbí

**Àkíyèsi:**

**Ẹ tún ògùn yìí lò tí ẹ bá bìí lẹ́yìn wákàtí méjì tí ẹ ti lò ó.**

Get it together
KNOW. TALK. GO.

NURHI 2
NIGERIAN URBAN REPRODUCTIVE HEALTH INITIATIVE

